


# ÌFÁÁRÀ

Sàfihàn araà rẹ jẹ́ ìṣẹ̀lẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́, àgbélé ṣe lórí ayélujára èyí tí o lè parí nígbà tí ó bá wù ẹ́! Wọ́n dá iṣẹ́ àkànṣe yìí láti mú ọwọ́ àwọn ènìyàn dilẹ̀ pẹ̀lú Ètò Àwọn Ènìyàn Glasgow, nípasẹ̀ iṣẹ́-ọnà, kíkó àwọn ènìyàn jọ àti fífi ọwọ́ wa ṣiṣẹ́ láti lè ṣàfihàn ìrètí, ìbẹ̀rù àti àfojúsùn wa nínú aṣọ fún Glasgow.

Ṣíṣàmúlò àmì oríléèdè Glasgow ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, a fẹ́ àwọn ẹgbẹ́, ẹbí àti ẹnìkọ̀ọ̀kan láti pín ìmọ̀ wọn lórí àwọn nǹkan tí yóò mú Glasgow dára sí i, tí á sì jẹ́ ibi tó ní ìfọ̀kànbalẹ̀ fún gbogbo ènìyàn láti gbé àti láti ṣiṣẹ́. Bákan náà ló wù wá kí ẹ lo aṣọ kékeré onígunmẹ́rin pẹ̀lú sísọ̀ọ̀sì, gúlúù, ohun ìránṣọ, káàdì, bọ́tíìnì, àṣọ láti fi yàwòrán èrò yín ,-ohunkóhun tí ẹ bá fẹ́!

Àwòrán yín le níṣe pẹ̀lú ohun tí àwọn àwòrán àmì oríléèdè túmọ̀ sí fún yin gẹ́gẹ́ bí ìrírí yín fún gbígbé ní Glasgow. Tàbí ó lè jẹ́ àwòrán ohun tí ẹ ní ìrètí tí ẹ sì fojúsùn pé Glasgow tó dára sí i lè jẹ́. Àwòrán náà lè tóbi ní ìwọ̀n 40cm (ogójì centimetre) á sì gùn ní ìwọ̀n 40cm (ogójì centimetre).

A ó wá to àwọn aṣọ onígunmẹ́rin yẹn pọ̀. Àwòrán tó tóbi yìí ni yóò jẹ́ aṣọ títẹ̀ tí ó ṣàfihàn Glasgow lọ́nà ọ̀tun.

Ìmísí èrò náà jeyọ nínú ìṣe ojọ́ pípẹ́ ti aṣọ títẹ̀, bánà ṣíṣe, iṣẹ́ ọnà, ìtakò àti yíyára. A óò ṣe àkọsílẹ̀ ètò ìṣiṣẹ́pọ̀ láti lè ṣe aṣọ títẹ̀, èyí tó wúlò bi iṣẹ́ tó ti parí. Bí a ṣe jọ ń ṣiṣẹ́ papọ̀ jẹ́ ara ṣíṣẹ̀dá ọ̀nà tuntun elétò èyí tó wúlò fún àwọn ará Glasgow.

Ìgbìmọ̀ ìlú Glasgow fi yé wa pé Àwọn Ènìyàn ló di Glasgow, nítorí náà, a fẹ́ gbogbo ènìyàn ní ojọ́ orí gbogbo àti ìpìlẹ̀ kan náà láti kópa nínú dídá ojọ́ ọ̀la Glasgow. Ṣíṣẹ̀dá aṣọ títẹ̀ yóò jẹ́ ọ̀nà láti mú ìbáṣepọ̀ láàrin wa àti ìlú wà dàgbà, àti bí a ṣe lè fi àwọn ènìyàn ṣáájú èrè.

# ÌMỌ̀ ÌPÌLẸ̀

## KÍN NI ÈTÒ ÀWỌN ÈNÌYÀN FÚN GLASGOW?

Ètò àwọn ènìyàn fún Glasgow jẹ́ àjọṣe ilé-iṣẹ́, ìpolongo àti ẹnìkọ̀ọ̀kan láti lè jọ ṣẹ̀dá ètò mìíràn fún àwọn ènìyàn àti ìlú. Ó ń fẹ́ láti yàtọ̀ gedegbe sí iṣẹ́ ńláǹlà tí wọ́n ti ṣe lóko lóri ìfinisílé, ìdájọ́ tó tọ́ fún àwọn aṣẹ̀ṣẹ̀wọ̀lú, ìlọkiri/ọkọ̀ wíwò, ètò ìlú, ìbádọ́gba, ìtọ́ni, ìlera àti ọrọ̀ ajé.

A PEOPLE'S PLAN FOR GLASGOW 2021

## KÍN NI ÀMÌ ORÍLẸ̀-ÈDÈ GLASGOW?

Àwọn àwòrán ìmísí ti àmì orílẹ̀-èdè Glasgow tipasẹ̀ olùdásílẹ̀ ìlú Glasgow wáyé, ìyẹn Mungo. Ọ̀rọ̀ àsàrò ti ìlú Glasgow 'Jẹ́ kí Glasgow ṣoríire' jẹ́ àfàyọ nínú ìwáásù Mungo. Igi náà ni a fi wé iná ti Mungo dá nípa lílò eyọ kan nínú ẹ̀ka-igi náà. Eyẹ Olongo ni èyí ti Mungo jí si ààyè. Eja náà ni sálúmọ̀ọ̀nì, tí wọ́n mú nínú odò Clyde. Ìtàn náà sọ pé Ọbabìnrin gba òrùka lọ́wọ́ ọkọ rè, ìyẹn Ọba. Ọbabìnrin náà wá fún olólùfẹ́ rè, èyí tó jù ú sínú odò Clyde. Ọkọ rẹ̀ ní kó mú òrùka náà wá kóun ri, ọpẹ́lọpẹ́ Mungo tó yọ òrùka náà nínú eja sálúmọ̀ọ̀nì tí ó sì dapadà fún Ọbabìnrin.




Àmì orílẹ̀-èdè Glasgow ló bí ewì yii:

*Igi kan wà tí kò hù rí*

*Eyẹ kan wà tí kò fò rí*

*Eja kan wà tí kò wẹ̀ rí*

*Aago kan wà tí kò dún rí*

# BÍ O ṢE LÈ KÓPA

1. Kàn sí wa nípa sísàmúlò àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tí ó wà nísàlẹ̀. O tún le mọ̀ si lóri iṣẹ́ àkànṣe yìí, wá àkókó láti gbé aṣọ àdìpò, kí o sì jẹ́ kí á mọ̀ tí o bá ní àfikún kankan!

2. Gba aṣọ àdìpọ̀! Aṣọ àdìpọ̀ onígunmẹ́rin, aṣọ ìlò onírúurú, àti irinṣẹ iṣẹ́ ọnà, ni a ti ṣètò sílẹ̀ ní Pearce Institute, nibi tí a ti ṣàyẹ̀wò wọn fin-ín fin-ín. A gbà ọ́ láyè láti ṣàmúlò awon ohun elo yii, tabi kí o ṣàmúlò àwọn ohun èlò tí o ti ní lọ́wọ́ tẹ́lẹ̀.

3. Wo fídíò yìí! Fídíò yìí ni yóò ṣe àlàyé ọ̀nà tí ènìyàn lè gbà ṣàfihàn èrò rẹ̀ lóri aṣọ onígunmẹ́rin.

4. Ṣẹ̀dá aṣọ onígunmẹ́rin re! Ṣe ju eyọ kan lọ bí èrò rẹ̀ bá pọ̀! O kò nílò ẹ̀bùn kankan láti kópa, ṣàmúlò àtinúdá rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe fẹ́!

5. Fi aṣọ onígunmẹ́rin rẹ sínú àpò tí a di aṣọ pọ̀ sí kí ó sì dáa padà sí Pierce Institute, yala kí o gbe wá síbẹ̀ fún araà rẹ tàbí kí o sàmúlò méèlì tí a ti sanwó rẹ̀.

6. Máa ṣọ́ ìkànnì àgbáyé abánidọ́ọ̀rẹ́ fún gbígbé lílo aṣọ onígunmẹ́rin rẹ̀ lóri ẹ̀rọ ayélujára.

7. Máa kàn sí wá lóòrèkóòrè lóri iṣẹ́ akanse yìí, láti mọ ibi iṣẹ́ dúró dé, àti títẹ́tí sí ìròyìn lórí ìpàdé ojúkorojú!

# Ọ̀NÀ ÌBÁNISỌRỌ̀

Bí o bá ní ìbéèrè yòówù ise akanse náà tàbí tí o kàn fẹ́ ní ìmọ̀ kún ìmọ̀, jọ̀wọ́ kàn sí wa lórí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ wọ̀nyí:

## ÀDÍRẸ̀SÌ

Ubuntu Women Shelter
2.07, 2nd Floor, The Pearce Institute
840-860 Govan Road, Glasgow
G51 3UU

## Ẹ̀RỌ ÌBÁNISỌ̀RỌ̀

**Ubuntu:** 0141 440 2072

## ÍMEÈLÌ

info@ubuntu-glasgow.org.uk
tàbí
ionasaneglasgow@gmail.com